# Àyẹ̀wò Ìlò Àpólà-Orúkọ Aṣẹ̀dá Nínú Ìwé Ìtàn-àròsọ *Àjà Ló Lẹrù*

Folúkẹ́ Bọ́láńlé Adékẹ̀yè & Bọ́láńlé Elizabeth Arókoyọ̀
Department of Linguistics and Nigerian Languages
University of Ìlọrin, Nigeria
bolanleadekeye@yahoo.com & bolakoyo@yahoo.com

## Àṣamọ̀

Ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè (linguistics) àti lítíréṣọ̀ ti wọnú ara wọn tí ó jẹ́ pé a fẹ́rẹ̀ má le ya ọ̀kan kúrò lára èkejì. Èròǹgbà iṣẹ́ yìí ni láti fi ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárin ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti lítíréṣọ hán. Láti ṣe èyí a yan ìwé-ìtàn –àròsọ Àjà Ló Lẹrù tí Òkédìjí kọ láàyò, a sì fi ẹ̀ka -ẹ̀kọ́ ìmọ̀ mọfọ́lọ́jì tí í ṣe ẹ̀kọ́ ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ nínú ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè ṣe àyẹ̀wò ìlò ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) aṣẹ̀dá nínú ìwé ìtàn-àròsọ yìí. Lára ọgbọ́n ìwádìí tí a lò ni pé a ka ìwé ìtàn àròsọ Àjà Ló Lẹrù dáadáa, a sì ṣe àfàyọ àwọn OR aṣẹ̀dá jáde nínú rẹ̀. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àkójọpọ̀ àti ìtúpalẹ̀ àwọn OR aṣẹ̀dá wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ìlànà ìṣẹ̀dá wọn nínú ẹ̀kọ́ mọfọ́lọ́jì. A ṣe àyẹ̀wò àwọn iṣẹ́ tí ó jẹ mọ́ mọfọ́lọ́jì àti ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ìsọwọ́lò-èdè àti lítíréṣọ̀ (stylistics) láti mú kí iṣẹ́ yìí kún ojú òsùnwọ̀n. Ní ìparí iṣẹ́ yìí, a rí i pé ipa tí ìlò àwọn OR aṣẹ̀dá nínú ìwé ìtàn-àrosọ yìí kó kò kéré rárá. Àwọn OR aṣẹ̀dá yìí jẹ́ èròjà tí ó mú èdè ìwé náà kún, kí ó ki tí ó sì fi àwòrán àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ hàn. Bí kò bá sí àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ lítíréṣọ̀, ọ̀pọ̀ ọ̀rọ̀ aṣẹ̀dá pàápàá OR nínu ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè ni kò ní wúlò bí a ṣe rí i nínú iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí. Lítíréṣọ̀ tún wá di orísun àfikún àká ọ̀rọ̀ nínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè.

## 1.0 Ìfáàrà

Ipa èdè kò kéré nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀ àti ní ìgbé ayé ọmọnìyàn. Èdè ni ó mú ayé rọrùn fún ọmọ ènìyàn láti gbé. Èdè ni a fi ń gbé èrò, ètò, ìmọ̀ lonírúurú kalẹ̀. Gbogbo ohun tí ẹ̀dá ń ṣe láyé èdè ni ó ń ṣe atọ́kùn àti atọ́nà fún wọn. Bí kò bá sí èdè, èrò, àrà tàbí ìmọ̀ tó wà nínú ẹ̀dá yóó rà síbẹ̀ bí ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀ ni láìní ìwúlò tí ó yẹ fún àwọn ènìyàn àwùjọ. Bí onímọ̀ sáyẹ́ǹsì ṣe àwárí ohunkóhun nínú ìwádìí rẹ̀, èdè ni yóó fi gbé ìmọ̀ tuntun bẹ̀ẹ̀ jáde kí ó tó lè wúlò láwùjọ. Nítorí

náà nínú gbogbo ẹ̀ka ìmọ̀ àti ẹ̀kọ́ ni èdè ti wúlò láìsọ àsọdún tàbí àsọrégèé. Abájọ tí Egbokhare (2004:507) ṣe sọ pé:

> Language permeates all aspects of human endeavour. It is a vehicle of culture and experience. It is the store of ideas and language provides for us different ways of looking at the world in addition to empowering us to think in different ways.
> (Èdè wọnú gbogbo ìgbìyànjú ọmọ ènìyàn. Òun ni ọkọ̀ tímó ń wa àṣà àti ìrírí ènìyàn. Èdè tún jẹ́ àká tí a ń to iyè-inú sí tí ó sì ń pèsè onírúurú ọ̀nà ìwòye ayé tí ó sì tún ń fún wa ní agbára láti ronú lọ́nà tí ó yàtọ̀ sí ara wọn).

Ohun tí Egbokhare (2004) sọ ni pè yàtọ̀ sí pé èdè jẹ́ ohun èlò ìronú, ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ yìí kan náà ni ọkọ̀ fún àṣà àwùjọ àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀. Ìdí nìyí tí dídùn tàbí àìdùn iṣẹ́ lítíréṣọ̀ fi dá lórí ìmọ̀ tí oníṣẹ́ lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ ní nínú èdè tí ó fi gbé iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ kalẹ̀. Oníṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ ní àǹfàní láti fi ọgbọ́n àtinúdá ṣe àmúlò èdè lọ́nà tí yóò fi rí ojú rere àwọn òǹkàwé rẹ̀ nígbà tí wọ́n bá kà á ní àkàgbádùn tí yóò sì mú kí iṣẹ́ náà jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ

Àǹfàní wà fún elédè láti ṣe àmúlò àwọn ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ nínú èdè rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni ó sì tún ní àǹfàní láti ṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn tuntun láti mú kí iṣẹ́ tí ó ṣe yàtọ̀ sí ti ẹlòmíràn. Gbogbo èdè ní àgbáyé ni ó ní irú àǹfàní yìí. Òkédìjí (1969) nínú ìwé ìtàn-àròsọ, Àjà Ló Lẹrù ṣe àmúlò ìmọ̀ ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun tí ó gbé iṣẹ́ yìí lárugẹ, tí ó sì mú kí ó jẹ́ àkàgbádùn fún gbogbo ọmọ káàárọ̀-oòjíire tí ó mọyì èdè abínibí wọn.

Àjà Ló Lẹrù ni ìwé tí ó jẹ́ ewé àkọ́já Alàgbà Òkédìjí nínú ìwé ìtàn àròsọ kíkọ kí àwọn iṣẹ́ mìíràn tó tẹ̀lé e. Ìdí nìyí tí a fi yan iṣẹ́ ọ̀hún láàyò fún wíwò nínù iṣẹ́ tí a ṣe yìí. Iṣẹ́ àkọ́ṣe báyìí máa ń fi ìmọ̀, òye àti àtinúdá òǹkọ̀wé hàn ju àwọn tí ó bá tẹ̀lé e. Ìdí ni pé àríwísí tí àwọn onímọ̀ bá ṣe sí iṣẹ́ àkọ́kọ́ máa ń hàn nínú àwọn iṣẹ́ mìíràn lẹ́yìn èyí tí ó kọ́ ṣe.

A fẹ́ láti fi ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè (linguistics) àti lítíréṣọ̀ hàn nínú iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí. Ọlátẹ́jú (2012:65) wòye pé: “Another development worthy of note, especially in Yorùbá scholarship is the increasing awareness in the role of linguistics in literary analysis and the growing relationship between linguistics and literary scholars”. Ohun tí Ọlátẹ́jú (2012:65) ń sọ ni pé ìdàgbàsókè tí ó yẹ fún àkíyèsí, pàápàá ninu ìmọ̀ ẹ̀kọ́ Yorùbá ni ìgbélárúgẹ ìbáṣepọ̀ ìlò ẹ̀kọ́ ẹ̀dá-èdè nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀ tí ó ń bí ìdàgbàsókè tí ó yẹ láàárín ẹ̀dá-èdè àti onímọ̀ lítíréṣọ̀. Nítorí ìdí èyí a fẹ́ láti fi kún ìmọ̀ tí ó wà nílẹ̀ nípa bí ìmọ̀ méjèèjì ṣe wọnú ara wọn, èyí sì ni ó mú wa dágbá lé iṣẹ́ yìí.

A lo ẹ̀ka ìmọ̀ mọfọ́lọ́jì tí ó jẹ ìlànà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ túntun, èyí tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè fún iṣẹ́ yìí. Ọ̀nà tí Alàgbà Òkédìjí gbà ṣe àmúlò àwọn OR aṣẹ̀dá tuntun nínú iṣẹ́ yìí fi òǹkọ̀wé náà hàn bí ẹni tí ó ní ìmọ̀ tí ó jinlẹ̀ nínú èdè Yorùbá. Ìṣẹ̀dá àti ìlò àwọn ọ̀rọ̀ tuntun ọ̀hún kàmọ̀mọ̀, ó gbóunjẹ fẹ́gbẹ́, ó

sì gbàwo bọ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí kò ṣe é fojú rénà nínú iṣẹ́ náà. Nítorí náà tíọ́rì mofọ́lọ́jì ni a lò láti ṣe àyẹ̀wò díẹ̀ nínú àwọn àpólà orúkọ, (APOR) tí ó kún inú iwé Òkédìjí yìí fọ́fọ́ọ́fọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Òkédìjí kò ní i lọ́kàn láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun kún àwọn tí ó wà nílẹ̀ nínú èdè Yorùbá lákòókò tí ó ń kọ ìwé yìí, gbẹ́nàgbẹ́nà rẹ̀ ti gbẹ ẹ́ tán, àwa gbẹ́nugbẹ́nu ni iṣẹ́ kù sí lọ́wọ́. Ara ojúṣe onímọ̀ èdè àti oníṣẹ́ láméyìítọ́ náà ni èyí tí a ṣe nínú iṣẹ́ yìí. A pín iṣẹ́ yìí sí abala mẹ́rin. Abala àkọ́kọ́ ni ìfáàrà, abala kejì ni a ti wo mofọ́lọ́jì. Ní abala kẹta àti kẹrin-in ni a ti ṣiṣẹ́ lórí àwọn ìlànà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tí a gbé yẹ̀wò. Ìkádìí ni ó sì gbẹ̀yìn nínú iṣẹ́ náà.

## 2.0 Mọfọ́lọ́jì

A lè pín àwọn ọ̀rọ̀ inú èdè kan sí ọ̀wọ́ méjì, ìpìlẹ̀ àti aṣẹ̀dá. A tilẹ̀ lè pè àwọn ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ inú èdè kan ní àtẹ́lẹwọ́ ni a bálà nítorí pé bí a ti bá wọn ni a ṣe ń lò wọ́n. Ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ ni àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ní mọ́fíìmù kan ṣoṣo àti ìtumọ̀ kan ṣoṣo, ọ̀rọ̀ àbáláyé ni wọ́n. Àwọn ọ̀rọ̀ aṣẹ̀dá ni àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ní ju mọ́fíìmù kan lọ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan mọ́fíìmù bẹ́ẹ̀ sì ní ìtumọ̀ tirẹ̀. Irú àwọn ọ̀rọ̀ yìí ni ẹ̀kọ́ mọfọ́lọ́jì dálé lórí.

Táíwò (2006: 3) ki mọfọ́lọ́jì bí "ẹ̀ka gírámà tí a ti máa ń kọ́ nípa ìhun ọ̀rọ̀. Èyí ni ẹ̀kọ́ nípa àwọn òfin tí ó jẹmọ́ ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀". Arókoyọ̀ (2013: 1) ki mọfọ́lọ́jì bí i, "... a branch of linguistics that deals with words, their forms, their internal structures and how they are formed". Èyí ni pé mọfọ́lọ́jì ni ẹka ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá – èdè tí ó ń ṣe àyẹ̀wò ọ̀rọ̀ inú èdè, ẹ̀yà wọn, èròjà wọn àti ìṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. Adékẹ́yè (2016: 11) sọ pé, "Mọfọ́lọ́jì ni abala ẹ̀kọ́ gírámá èdè tí ó níṣe pẹ̀lú ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun nípa ìlò àwọn wúnrẹ̀n kan tí a mọ̀ sí mọ́fíìmù". Nínú àwọn oríkì àwọn onímọ̀ mẹ́ta yìí, a rí i pé ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun ni ẹ̀kọ́ mọfọ́lọ́jì jẹmọ́. Gbogbo èdè ní àgbáyé ni ó ní àǹfàní yìí. Òfin àti ìlànà tí èdè kọ̀ọ̀kan ń ṣe àmúlò rẹ̀ sì yàtọ̀ sí ti èdè mìíràn.

Bí àwọn wúnrẹ̀n tí a mọ̀ sí mọ́fíìmù wọ̀nyí ṣe ń papọ̀ di ọ̀rọ̀ tuntun yàtọ̀ láti ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ kan sí èkejì nínú èdè Yorùbá. Iyé mọ́fíìmù tí ó sì le papọ̀ di ọ̀rọ̀ kan kò ní ìdiwọ̀n nínú èdè Yorùbá. Onírúurú ìlànà ni gírámà èdè Yorùbá ń ṣe àmúlò láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun. Lára àwọn ìlànà yìí ni:

-lílo àfòmọ̀ ìbẹ̀rẹ̀ àti ti ààrín;
-àpétúnpè kíkún tàbí / àti ẹlẹ́bẹ;
-àkànpọ̀ mọ́fíìmù ìpìlẹ̀ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ;
-ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun (OR) láti ara awẹ́/ odidi gbólóhùn; àti
-ìṣẹ̀dá nípa ìlànà àyálò ọ̀rọ̀ láti inú èdè mìíràn.

Púpọ̀ nínú àwọn ìlànà mọfọ́lọ́jì wọ̀nyí ni Òkédìjí (1969) lò nínú ìwé rẹ̀ Àjà Ló Lẹrù tí à ń gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí, a fẹ́ kí á mọ̀ pé Òkédìjí kò ní ìṣẹ̀dá àwọn

ọ̀rọ̀ wọ̀nyí lọ́kàn nígbà tí ó dáwọ́ lé iṣẹ́ yìí. Nítorí ó jẹ́ agbédè-gbẹ́yọ̀, tí ó sì mọ èdè abínibí rẹ̀ dọ́ba ni ìkẹ́kọ̀ọ́ tí a ń gbé yẹ̀wọ̀ yìí ṣe jẹ́ ṣíṣe.

Bí a bá sọ pé gbogbo ìlànà tí a tò sókè wọ̀nyí ni Òkédìjí lò láìmọ̀, a kò jayò pa rárá. Àwọn àpẹẹrẹ gbogbo ìlànà mọfọ́lọ́jì yìí ni ó kún inú ìwé yìí láti ìbẹ̀rẹ̀ dé ìparí. A kò ní wò ju àwọn ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) / àpólà orúkọ (APOR) lọ pẹ̀lú ipa tí àwọn OR aṣẹ̀dá náà kó nínú iṣẹ́ yìí, nítorí pé èyí ni àfojúsùn wa. A kò ṣàlàyé àwọn ìlànà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ní abala yìí kí ó má baà fa àwítúnwí àti àsọtúnsọ nínú iṣẹ́ náà. A óó máa ṣàlàyé wọn bí a bá ṣe ń bá iṣẹ́ yìí lọ.

## 3.0 Àwọn Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣẹ̀dá àti Ipa tí Wọ́n kó Nínú Ìtàn Àjà Ló Lẹrù

Ní abala yìí, a óó wo àwọn OR aṣẹ̀dá gẹ́gẹ́ bí ìlànà ìṣẹ̀dá wọn àti ipa tí wọ́n ní lórí ìtàn inú ìwé tí à ń wò yìí.

### 3.1. Àwọn Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣẹ̀dá Nípa Ìlànà Àfòmọ́ Ìbẹ̀rẹ̀.

Gbogbo fáwẹ̀lì àìránmúpè inú èdè Yorùbá ni a lè so mọ́ ọ̀rọ̀-ìpìlẹ̀ àyàfi fáwẹ̀lì gíga ẹ̀yìn roboto /u/. Ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí àpólà ìṣe ni a sábà máa ń ta àwọn fáwẹ̀lì àìránmúpè wọ̀nyí mọ́, ọ̀rọ̀-orúkọ sì ni àmújáde bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́. Tí a bá gùnlé àlàyé Owólabí (1995), ó ní, ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí àpólà-ìse ni a máa ń so àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ yìí mọ́ láti ṣẹ̀dá OR. Láti ìbẹ̀rẹ̀ ìwé Àjà Ló Lẹrù dé òpin rẹ̀ ni a ti rí àpẹẹrẹ irú àwọn OR aṣẹ̀dá báyìí. Àwọn àpẹẹrẹ OR aṣẹ̀dá bẹ́ẹ̀ ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

Àpẹẹrẹ 1:

(a) Akúra ⟶ a + kú + ara (o.i. 3)

(b) Aṣebi ⟶ a + ṣe + ibi (o.i. 7)

(d) Ajáwó ⟶ a + já + owó (o.i. 21)

(e) Agbowóopá ⟶ a + gba + owó + ipá (o.i. 35)

(ẹ) Afàkàrà-jẹ̀ko-sùn ⟶ a+ fi + àkàrà+ jẹ + ẹ̀kọ + sùn (o.i. 44)

(f) Ajíyàngbé ⟶ a + jí + ènìyàn + gbé (o.i. 44)

(g) Afábẹ̀lá ⟶ a+ fá + ọbẹ̀ + lá (o.i.44)

(gb) Akọgbatúgbaká ⟶ a + kọ + igba + tú + igba + ká (o.i. 144)

(i) Agbingbótugbónù ⟶ a + gbin + igbó + tu + igbó + dànù (o.i. 144)

(h) Aṣiṣẹ́basẹ́jẹ́ ⟶ a + ṣiṣẹ. + ba + iṣẹ́ + jẹ́ (o.i. 44)

(j) Afúnjàá –ma-pọnmọ ⟶ a+ fún + ọ̀já + má + pọn + ọmọ

Bí a bá wo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí, a ó rí i pé ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn mọ́fíìmù àmújáde wọ̀nyí jẹ́ àpólà orúkọ (APOR). Mọ́fíìmù tí ó wà nínú ipò tí àfòmọ̀ ìbẹ̀rẹ̀ /a/ wà nínú ìhun tí a ti sẹ̀dá ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni /ẹni tí ó /, (òǹṣe) + Àpólà Ìṣe (APIS). Ẹ́ jẹ́ kí a wo díẹ̀ lára àwọn àpẹẹrẹ yìí lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́


Àpẹẹrẹ 2:

(a) a + ṣe + ibi ⟶ ẹni tí ó ṣe ibi

(b) a + kọ +igba + tú + igba + ká ⟶ ẹni tí ó kọ igba (ebè) tí ó tú igba (ebè) ká

(d) a + jí + èniyàn + gbé ⟶ ẹni tí ó jí èniyàn gbé

Àpẹẹrẹ 3:




aṣebi

Bí a bá wo àwọn gbólóhùn tí a ti mú àpẹẹrẹ (gb-h) jáde nínú ìwé *Àjà Lo Lẹr*ù, a ó ri pé àwọn OR aṣẹ̀dá tí òǹkọ̀wé lò níbẹ̀ mú kí gbólóhùn náà dùn léti, tí ó sì tún mú kí ó kúrú sí i ju kí ó fi ìhun gígùn sọ ohun tí ó fi OR ìṣẹ̀dá sọ lọ. Ẹ jẹ́ kí a kúkú wo àwọn gbólóhùn méjèèjì yìí:

**Àpẹẹrẹ 4:**

…. Rẹ́gí rẹ̀ ló ṣe. **Akọgbatúgbaká**. Ṣùgbọ́n tirẹ̀ yàtọ̀ díẹ̀. **Agbingbótugbónù** ni. **Aṣiṣẹ́baṣẹ́jẹ́**. (o.i.144).

Dípò kí òǹkọ̀wé sọ pé,

**Àpẹẹrẹ 5:**

…. Rẹ́gí rẹ̀ ló ṣe. Ẹni tí ó kọ igba ebè tí ó tú igba ebè ká. Ṣùgbọ́n tirẹ̀ yàtọ̀ díẹ̀. Ẹni tí ó gbin igbó tí ó tu igbó dànù ni. Ẹni tí ó ṣiṣẹ́ tí ó ba iṣẹ́ jẹ́.

Bí àwọn OR ìṣẹ̀dá mẹ́tẹ̀ẹta tí a kọ yàtọ̀ mú kí ó dùn bí wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn tí wọ́n sì bá ara wọn mu rẹ́gírẹ́gí jẹ́ ara ohun tí ó fi iṣẹ́ ẹni tí ó nímọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú èdè Yorùbá hàn. Irú ìpèdè yìí kì í ṣe ti ọ̀gbẹ̀rí nínú ìmọ̀ èdè rárá. Yàtọ̀ sí èyí, ìlò àwọn OR ìṣẹ̀dá wọ̀nyí fi irú ìwà àti ìṣe ẹ̀dá ìtàn, Gbékútà jẹ́ hàn. Èyí ni ìdí tì òǹkọ̀wé ṣe fi Gbékútà tì ò gbin igbó tí ó tún gba àwọn tí ó bá a tu igbó ọ̀hún dànù, tí ó ṣe iṣẹ́ tí ó ba iṣẹ́ ara rẹ̀ jẹ́ wé bàbá kan tí ó torí aásàà tú igba ebè tí ó fi ààrọ̀ ọjọ́ kọ ká. A rí ìwà alájàǹbàkù àti aláìlárò-jinlẹ̀ nínù bàbá Akọgbatúgbaká àti Gbékútà, Agbingbótugbónù, Aṣiṣẹ́baṣẹ́jẹ́. Bí ó bá jẹ́ gbólóhùn tí a kọ gbẹ̀yìn ni Òkédìjí lò ni, ìmọ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn méjì yìí kò ní hànde báyìí.

### 3.1.2. Àwọn Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣẹ̀dá Nípa Ìlànà Àfòmọ́ Ìbẹ̀rẹ̀ /àì-/

Mọ́fíìmù àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ afarahẹ yìí, /àì/ jẹ́ èyí tí ó máa ń fi ìtumọ̀ òdì hàn yàtọ̀ sí ti ojú. Ọ̀rọ̀ tàbí àpólà ìṣe ni a máa ń ta àfòmọ́ yìí náà mọ́ nínú gírámà, OR sì ni àmújáde rẹ̀ máa ń jẹ́. A fẹ́ wo àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀ nínú àwọn OR aṣẹ̀dá yìí àti ìlò wọn nínú Àjà Ló Lẹrù tí Òkédìjí kọ;

Àpẹẹrẹ 6:

a. àìsínílé ⟶ àì+sí+ ní+ ilé (o.i. 1)

b. àìlera ⟶ àì+ le+ ara (o.i 2)

d. àìgbádùn ⟶ àì+ gbé (ayé) + adùn (o.i.2)

e. àìríṣẹ́ṣe ⟶ àì + rí + iṣẹ́ + ṣe (o.i. 49)

ẹ àìrílégbé ⟶ àì+ rí + ilé + gbé (o.i. 49)

f. àìmète ⟶ àì + mọ+ ète (o.i 138)

g. àìmèrò ⟶ àì + mọ + èrò (o.i 38)


Bí òǹkọ̀wé kò bá lo àwọn OR aṣẹ̀dá wọ̀nyí, ọ̀nà míràn tí ó lè fi sọ àwọn èrò tí ó fi àwọn ọ̀rọ̀ ọ̀hún gbé kalẹ̀ wọ̀nyí nìyí ni 7 (a –g) ní sísẹ̀-n-tẹ̀lé

**Àpẹẹrẹ 7:**

a. kí èèyàn má sí í ní ilé.
b. kí ara èèyàn má le
d. kí èèyàn má gbé ayé adùn
e. kí èèyàn má rí iṣẹ́ ṣe
ẹ. kí èèyàn má rí ilé gbé
f. kí èèyàn má mọ ète
g. kí èèyàn má mọ èrò

Àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ /àì-/ lásán ni ó dípò awẹ́ gbólóhùn '**kí èèyàn má**' nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àpẹẹrẹ (7) tí òǹkọ̀wé ta mọ́ APIS kọ̀ọ̀kan láti fi ṣẹ̀dá àwọn OR tí ó lò nínú àwọn ojú ìwé tí wọ́n ti jẹyọ. Àpẹẹrẹ ìlànà ìṣẹ̀dá wọn nìyí ní (8)

**Àpẹẹrẹ 8:**




Àwòrán tí ó wà ní (8) yìí fihàn pé àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ (Afb) /àì/ ni a ta mọ́ àpólà-ìṣe (APIS) láti ṣẹ̀dá OR aṣẹ̀dá tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí.

Ó yẹ kí a wo gbólóhùn tí òǹkọ̀wé ti lo díẹ̀ nínú àwọn OR aṣẹ̀dá tí à ń yẹ̀wò yìí:

Àpẹẹrẹ 9: … Wọ́n ní **<u>àìmète, àìmèrò</u>** lọmọ ìyá mẹ́fà fi kú sóko ẹgbàafà

Bí òǹkọ̀wé kò bá lo àwọn OR aṣẹ̀dá wọ̀nyí ni, gbólóhùn òkè yìí ìbá jẹ́ (10):

Àpẹẹrẹ 10: Wọ́n ní kí èèyàn má mọ ète kí ènìyàn má mọ èrò ni ọmọ ìyá mẹ́fà
fi kú sóko ẹgbàafà

Ìlò èdè inú gbólóhùn (9) mú kí ó dùn, ó sì tún kúrú ju ti àpẹẹrẹ (10). Yàtọ̀ sí èyí, ìlò èdè inú àpẹẹrẹ (10) kìí ṣe ti onímọ̀ kíkún nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀, ó kàn rí ṣákálá bí ẹni tí kò gbọ́ èdè dáadáa. Irú OR aṣẹ̀dá yìí àti bí òǹkọ̀wé ṣe lò wọ́n pọ̀ jẹ́ ara ọgbọ́n ìkọ̀tàn tí ó mú kí iṣẹ́ náà wuyì. Ìlò èdè yìí tún fi Lápàdé, olú ẹ̀dá-ìtàn hàn bí ẹni tí ó gbọ́n tí ó sì le yàra ronú láti mọ ẹ̀yìn ọ̀rọ̀ èyí tí ó jẹ́ ara àwọn àmúyẹ tí olú ẹ̀dá-ìtàn máa ń ní.

### 3.1.3 Àwọn Ọ̀rọ̀-orúkọ Aṣẹ̀dá Nípa Ìlànà Ọ̀rọ̀ Àyálò.

Ìlànà ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun nípa ọ̀rọ̀ àyálò jẹ́ kárí ayé. Gbogbo èdè ni ó máa ń yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè mìíràn, nítorí kò sí èdè tí ó tó tán. Àwọn onímọ̀ gírámà bí Awobuluyi (2002), Taiwo (2006) àti Adékẹ́yè (2016) wà lára àwọn tí ó fi ìdí èyí múlẹ̀ nínú mọfọ́lọ́jì èdè Yorùbá. Gbogbo èdè tí ó bá yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè mìíràn tí ìhun fonọ́lọ́jì rẹ̀ yàtọ̀ máa ń mú ọ̀rọ̀ tuntun bẹ́ẹ̀ bá ìhun fonọ́lójì èdè tí wọ́n yá a wọ̀ mu. Èyí kò yọ èdè Yorùbá sílẹ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé èdè kọ̀ọ̀kan ni ó ní òfin gírámà tirẹ̀ tí ó sì lè má jọ ti èdè mìíràn. Èdè Yorùbá sábà máa ń yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì, Hausa àti èdè Lárúbáwá. Ọ̀rọ̀ àyálò láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì ni ó wọ́pọ̀ jù nínú èdè Yorùbá. Ìmọ̀-ẹ̀rọ, kọ̀mpútà àti ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì ni ó sì fa èyí. Ìlànà orísìí méjì tí Yorùbá fi ń yá ọ̀rọ̀ ni ìlànà àfetíyá àti ìlànà àfojúyá. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni àwọn tí ó yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè mìíràn wọ èdè Yorùbá kì í funra pé wọ́n ṣe àmúlò ìlànà kan tàbí èkeji.

Ọ̀rọ̀ àyálò láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì ni Òkédìji lò jù nínú ìwé ìtàn àròsọ, Àjà Ló Lẹrù tí a ń gbé yẹ̀wò yìí bẹ́ẹ̀ ni ó sì ṣe àmúlò wọn bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ ni. Òǹkọ̀wé tún mú kí àwọn ọ̀rọ̀ náà bá òfin fonọ́lọ́jì èdè Yorùbá mu bí ó ti yẹ. Ní báyìí, a óò ṣe àyẹ̀wò àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀ láti inú ìwé náà.

**Àpẹẹrẹ 11:**

| | **Ọ̀rọ̀ àyálò** | **Ojú ìwé** | **Èdè Gẹ̀ẹ́sì** |
|---|---|---|---|
| a. | kọmísọ́nnà | 2, 14, 62 | Commissioner |
| b. | sẹkitéríà | 2, 51 | secretariat |
| d. | Kélẹ́ẹ̀bù | 2 | Caleb |

| | | | |
|---|---|---|---|
| e. | kọ́bùrù | 2, 62 | corporal |
| ẹ. | báńkì | 13 | bank |
| f. | síńgílẹ́ẹ̀tì | 17 | singlet |
| g. | sánmọ́ńtì | 34 | cement |
| gb. | wíńdò | 54 | window |
| i. | sọ́jà | 84 | soldier |
| h. | bẹ́tíkù | 64 | spectacles |
| j. | bèbí | 142 | baby (toy) |
| k. | báláǹsì | 96 | balance |

A rí i pé àwọn OR àyálò wọ̀nyí pọ̀ dọ́ba nínú ìwé Àjà Ló Lẹrù ṣùgbọ́n a kan fa díẹ̀ yọ nínú wọn ni. Bí òǹkọ̀wé ṣe mú àwọn ọ̀rọ̀ ọ̀hún lò gẹ́lẹ́ ni a ṣe kọ wọ́n jáde yìí. A sì rí i pé kò sí èyí tí ó tako ìlànà tàbí òfin fonọ́lọ́jì Yorùbá nínú wọn. Àwọn ọ̀rọ̀ náà kò ní ìṣùpọ̀ kọ́ńsónáǹtì tàbí kí kọ́ńsónáńtì gbẹ̀yìn wọn. Gbogbo àwọn tí ó ni ìṣùpọ̀ kọ́ńsónáǹtì nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí tí kọ́ńsóńaǹtì gbẹ̀yìn wọn ni òǹkọ̀wé ti ṣiṣẹ́ lé lórí láti mú kí wọ́n bá ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ èdè Yorùbá mu.

Bí a bá wo àwọn OR àyálò tí a fàyọ wọ̀nyí, a óó rí i pé kì í ṣe pé kò sí ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá tí òǹkọ̀wé lè lò, ṣùgbọ́n ó mọ̀n-ọ́n-mọ̀ fi àwọn OR àyálò wọ́nyì sí ẹnu àwọn akópa tí wọ́n lo àwọn ọ̀rọ̀ náà láti fi wọ́n hàn bí ẹni tí ó kàwé tí ó sì lajú ni. Èyí tí ó pọ̀jù nínú àwọn OR àyálò wọ̀nyí ni ó jẹ́ pé ẹnu òǹkọ̀wé àti Lápàdé tí ó jẹ́ olú ẹ̀dá-ìtàn ni a ti gbọ ọ.

Díẹ̀ nínú OR àyálò Yorùbá tí òǹkọ̀wé lè lò dípò àwọn àyálò ọ̀hún nìyí ní 12.

**Àpẹẹrẹ 12:**

| | Gẹ̀ẹ́sì | Yorùbá |
|---|---|---|
| a. | commissioner | aláṣẹ |
| b. | secretariat | ilé-iṣẹ́ ìjọba |
| d. | corporal | oyè ológun |
| e. | bank | ilé-ìfowópamọ́ |
| ẹ. | singlet | ẹ̀wu-àwọ̀tẹ́lẹ̀ |
| g. | cement | ìyẹ̀fun-òkúta |
| gb. | window | fèrèsé |
| i. | soldier | ọmọ-ogun |
| h. | spectacles | awò-ojú |
| j. | baby (toy) | ìṣeré-oníke |
| k. | balance | ṣe déédé |

Ó yẹ kí a fa àwọn gbólóhùn díẹ̀ tí Òkédìji ti lo àwọn OR àyálò wọ̀nyí jáde, kí a wá ṣe àfiwé wọ́n mọ́ ẹ̀yà gbólóhùn náà tí a ti lo ẹ̀yà Yorùbá wọn, kí a wo èyí tí ó má a dùn jù létí nínú àwọn àpẹẹrẹ 13.

**Àpẹẹrẹ 13:**

(a) Àmọ̀ kí ni kí Kọmíṣọ́nnà ṣe? (o.i 2)
(b) A wá ḿ bẹ Kọmíṣọ́nnà àwọn ọlọ́pàá yìí pé kí ó ta àwọn ọmọṣẹ́ rẹ̀ jí. (o.i 14-15)
(d) Àmọ̀ kí ni kí aláṣẹ ṣe?
(e) A wá ḿ bẹ aláṣẹ àwọn ọlọ́pàá yìí pé kí ó ta àwọn ọmọṣẹ́ rẹ̀ jí.

Àpẹẹrẹ 14:
(a) Wọn kò rẹ́ ilé náà ní sánmọ́ńtì (o.i 34)
(b) Wọn kò rẹ́ ilé náà ní ìyẹ̀fun-òkúta.

Nínú àwọn àpẹẹrẹ 13 a fa gbólóhùn (a) àti (b) yọ nínú ìwé Àjà Ló Lẹrù bí òǹkọ̀wé ṣe lò ó. Àpẹẹrẹ (d) àti (e) jẹ́ ẹ̀dà tí a fi OR Yorùbá tí ó dúró fún OR àyálò. A rí i pé àwọn gbólóhùn (a) àti (b) dùn, wọ́n mú òye kíkún irú aláṣẹ tí ọ̀rọ̀ tó ń lọ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé náà ní pàtó kàn hàn. Ìpele-ìpele ni àwọn oyè nínú iṣẹ́ ọlọ́pàá. Olúkálùkù àwọn ìpele yìí ni o ní aláṣẹ tirẹ̀ tí ó ń darí. Nítorí náà ìlò *kọmíṣọ́nnà* jẹ́ kí a mọ̀ ipele aláṣe tí ọ̀rọ̀ wà lọ́wọ́ rẹ̀ ní àkókò náà.

Bí a bá tún wo àpẹẹrẹ 14, a fa gbólóhùn (a) yọ nínú ìwé tí a ń wò bí òǹkọ̀wé ṣe fi ìlò rẹ̀ sí ẹnu Lápàdé nígbà tí Tàfá ń mú lọ sílé Jàǹpàkò. Gbólóhùn (b) jẹ́ ẹ̀dà tí a ti lo ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀ Yorùbá dípò OR àyálò tí òǹkọ̀wé lò. A rí i pé, gbólóhùn 14 (a) tètè yé òǹkàwé ju kí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ má a ronú ohun tí ìyẹ̀fun-òkúta jẹ́. Nítorí náà ìlò àwọn OR àyálò nínú ìwé náà bá a mu rẹ́gírẹ́gí ni bí ojú tí o ti kékeré fọ́. Àwọn OR àyálò wọ̀nyí sì jẹ́ kí ìtàn náà dùn kí ó sì gbóúnjẹ fẹ́gbẹ́ pẹ̀lú. Irú ìlò èdè yìí mú kí ìtàn àròsọ náà jẹ́ èyí tí ó bá ìgbà mu. Aṣọ ìgbà sáà ni à ń dá fúngbà, kí í ṣe kìkì àwọn tí kò gbọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì ni ó máa ń ka ìwé ìtàn-àròsọ. Àwọn agbédè-gbẹ́yọ̀ náà wà nínú àwọn òǹkàwé. Ìdí yìí kan náà ni Òkédìjí ṣe fi èdè àdúgbò sí ẹnu ìyá àgbà àti Sẹ̀lí ní Ikérékú, ìletò kan lára ibùdó ìtàn tí Lápàdé àti Tàfá wá àwọn gbọ́mọgbọ́mọ lọ. A rí i pé èdè tí òǹkọ̀wé fi sí ẹnu àwọn ẹ̀dá-ìtàn báwọn àti ibùdó wọn mu.

### 3.1.4 Ìlànà Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀-orúkọ Láti Ara apólà-ìṣe Nípa Àpètúnpè Kíkún.

Àpètúnpè kíkún lè jẹ́ ti APOR tàbí APIS nínú gírámà èdè Yorùbá. Èyíkéyìí tí a bá ṣe àpètúnpè rẹ̀ nínú méjèèjì, OR ni àbájáde rẹ̀ máa ń jẹ́ (Adékẹ́yè 2016). Àkànpọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe àti ọ̀rọ̀-orúkọ ni ó má a ń kọ́ ṣẹ̀lẹ̀ kí àpètúnpè kíkún tí yóò di OR tó wáyé. Àpẹẹrẹ nìyí nínú gírámà Yorùbá.

Àpẹẹrẹ 15:

| IS | + | OR | → | IS | → | Àpètúnpè (OR) |
|---|---|---|---|---|---|---|
| (a) | wo | | ilé | | wolé | woléwolé |
| (b) | gbá | | ilẹ̀ | | gbálẹ̀ | gbálẹ̀gbálẹ̀ |
| (d) | gbẹ́ | | ọnà | | gbẹ́nà | gbẹ́nàgbẹ́nà |
| (e) | la | | eegun | | lagun | lagunlagun |

| | | | |
|---|---|---|---|
| (ẹ) | sọ | ọ̀rọ̀ | sọ̀rọ̀ sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ |

A rí i pé ìsúnkì ni ó kọ́kọ́ wáyé láàárín IS àti OR tí ó fún wa ní IS tí a ṣe àpètúnpè rẹ̀ kí a tó ní OR tí ó jẹ́ àmújáde. Nínú ìwé Àjà Ló Lẹrù tí à ń wò yìí, a rí ìlò àwọn OR aṣẹ̀dá nípasẹ̀ àpètúnpè kíkún tí a sọ yìí tí ó sì kó ipa pàtàkì tí ó mú kí ìtàn nàá dùn kí ó tún lóyin. Ẹ jẹ́ kí a wo díẹ̀ nínú irú àpẹẹrẹ bẹ́ẹ̀.

**Àpẹẹrẹ 16:**

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| (a) | dá + ara | dára | dáradára | (o.i 1) |
| (b) | ta + igbó | tagbó | tagbótagbó | (o.i 3, 13) |
| (d) | dun + ara | dunra | dunradunra | (o.i 13) |
| (e) | gbé + ọmọ | gbọ́mọ | gbọ́mọgbọ́mọ | (o.i 15, 68) |
| (ẹ) | ná + owó | náwó | náwónáwó | (o.i 33) |
| (f) | dá + ọ̀nà | dánà | dánàdánà | (o.i 44) |
| (g) | pa + ẹyẹ | pẹyẹ | pẹyepẹye | (o.i 59) |

Bí a bá wo àwọn gbólóhùn tí Òkédìji ti ṣe àmúlò àwọn OR aṣẹ̀dá nípa ìlànà àpètúnpè kíkún wọ̀nyí, a óó rí i pé kì í ṣe pé kò lè sọ àwọn èrò ibẹ̀ jáde láìlò wọn. Bí àpẹẹrẹ.

**Àpẹẹrẹ 17:**

(a) Bí ìwẹ̀ kò ṣeé wẹ̀, òun ó bójú-bọ́sẹ̀, òun ó sì wá mú aṣọ dáradára wọ̀ (o.i 1)

(b) Bí ìwẹ̀ kò ṣeé wẹ̀, òun ó bójú-bọ́sẹ̀, òun ó sì wá mú aṣọ tí ó dára wọ̀.

**Àpẹẹrẹ 18:**

(a) Kò lè dá adìyẹ mú ká tó sọ pé àwọn tagbótagbó. (o.i 3)

(b) Kò lè dá adìyẹ mú ká tó sọ pé àwọn ẹni tí ń ta igbó.

**Àpẹẹrẹ 19:**

(a) Iṣẹ́ jàgùdà ni òun ń ṣe àbí iṣẹ́ dánàdánà? (o.i 44)

(b) Iṣẹ́ jàgùdà ni òun ń ṣe àbí iṣẹ́ ẹni tí ó ń dá ọ̀nà?

Nínú àpẹẹrẹ (17-19), àwọn àpẹẹrẹ (a) jẹ́ èyí tí Òkédìji ti fi ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ rẹ̀ nínú èdè Yorùbá hàn tí ó sì lo àwọn OR aṣẹ̀dá ní ìlànà àpètúnpè kíkún tí a ń yẹ̀wọ̀. Àwọn àpẹẹrẹ (b) jẹ́ ọ̀nà mìíràn tí òǹkọ̀wé lè gbà sọ àwọn gbólóhùn (a). A rí i pé àwọn àgbékalẹ̀ (b) kò wọ ni lára tàbí mú ni lọ́kàn bí i ti àwọn (a) tí òǹkọ̀wé lò. Ìlò irú àwọn ọ̀rọ̀ yìí fún ìtàn náà ní ìwọ̀n tí ó lóòrìn.

## 4.Ìlò Ọ̀rọ̀-orúkọ Idiofóònù.

OR idiofóònù ni àwọn OR kan tí àmì ohùn orí fáwèlì wọn máa ń fi ìrísí wọn hàn. Ìdí nìyí tí a fi tún máa ń pè wọ́n ní Fìró-mọ̀rísí. Bí àwọn àmì ohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ṣe ń fi ìrísí hàn nìyí.

**Àpẹẹrẹ 20:**

(a) jágbajàgba
(b) kátikàti

**Àpẹẹrẹ 21:**

(a) gbàǹgbàgbangba
(b) kàbìtìkabiti

**Àpẹẹrẹ 22:**

(a) kóńkókó
(b) róbótótó

Àwọn àpẹẹrẹ 20 níbi tí ohùn òkè, ààrín, ìsàlẹ̀ àti ohùn ààrín ti tẹ̀lé ara wọn ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé fi ìrísí àìbójúmu hàn. Àwọn àpẹẹrẹ 21 tí ohùn ìsàlẹ̀ mẹ́ta ti sáájú ohùn ààrín mẹ́ta fi ìrísí ohun tí ó tóbi hàn. A rí àmì ohùn òkè tí ó tẹ̀lé ara wọn tí ó sì fi ìrísí ohun kékeré hàn ní àpẹẹrẹ 22. A rí ìlò irú àwọn OR aṣẹ̀dá yìí tí òǹkọ̀wé lò ní àlògbádùn. Díẹ̀ nínú àwọn gbólóhùn tí a ti rí ìlò OR aṣẹ̀dá bẹ́ẹ̀ nìyí ni 23 tí òǹkọ̀we ti ń ṣe àpèjúwe Tíàmíyù, ọ̀kan lárá àwọn ọ̀daràn tí Lápàdé ń wá kiri níú ìtàn náà.

Àpẹẹrẹ 23: Tìámíyù tó <u>gèlètègelete</u>, ó bààyàn lẹ́rù láti wò. Ó rí <u>gòlọ̀tọ̀golọto</u> (o.i 79)

Ìlò àwọn OR wọ̀nyí tí wọ́n ní àmì ohùn kan náà yìí ń fi bí Tìámíyù ti tóbi tó hàn. A tún rí àwọn àpẹẹrẹ mìíràn nígbà tí òǹkọ̀wé ń sọ fún òǹkàwé bí Tàfá, ọmọ ẹ̀yìn Lápàdé ṣe fiyà jẹ Tìámíyù nílé rẹ̀ tí wọ́n lọ káa mọ́.

Àpẹẹrẹ 24: Tàfá tún ń lù ú bí ẹran. Ó ṣe é <u>pásapàsa</u>, ó ṣe é <u>síboṣìbo</u> … Tàfá kò fi sílẹ̀ títí ó fi sọ ọ́ di <u>játijàti</u> (o.i 156)

Àwọn OR idiofóònù mẹ́ta tí a fàlà sí ní ìdí nínú àyọlò nọ́ńbà 24 yìí fi hàn bí Tàfá ṣe lu Tìámíyù ní ìlùkulù, ní ọ̀nà tí kò fi jẹ́ ojú rí mọ́. Báyìí a rí bí òǹkọ̀wé ṣe fi onírúurú OR aṣẹ̀dá dára sínú iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ yìí tí ó sì sọ ìwé náà di èyí tí ènìyàn lè kà nígbà àìmọ̀ye tí kò sì ní ṣú olúwarẹ̀. Òǹkọ̀wé fi OR idíófóònù

yàwòrán bí Tìàmíyù ṣe tóbi tó han òǹkàwé; ó tún fi àwọn OR ídíófóònù mìíràn yàwòrán bí Tàfá ṣe lu ẹni tí ó tóbi tó yìí.

## 4. Ìkádìí

Iṣẹ́ yìí jẹ́ ara ìdáhùn sí ìpèníjà àti ìpè Owólabí (1992) sí àwọn onímọ̀ èdè Yorùbá láti kíyèsí ipa tí ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè lè kó nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀. Síwájú sí i, iṣẹ́ yìí fìdí ohun tí Ọlábọ̀dé (1985) sọ pé onímọ̀ méjèèjì jọ ń gbé iṣẹ́ ara wọn lárugẹ ni. Onímọ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀ ń ṣe àmúlò èdè lọ́nà tí ó mú kí àká-ọ̀rọ̀ kún sí i nínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè. Bí àpẹẹrẹ, bí a bá wo bí òǹkọ̀wé ṣe mú kí Tàfá ki ara rẹ̀:

...abojúúbọmọlẹ́rù, olójúu-bá-mi-dẹ́rù-bọmọ-mi, ...ayà-jin-mọ-gìrìgìrì...(o.i 61)

Àwọn OR aṣẹ̀dá tí Òkédìjí fi sí ẹnu Tàfá, inú iṣẹ́ lítíréṣọ̀ ni ìlò wọn ti ṣe é ṣe, bí wọ́n tilẹ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀ aṣẹ̀dá nínú ìmọ̀ èdá-èdè. A fẹ́ fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé abala kan nínú ìlò èdè ni a gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí. Nínú ohun tí ó mú kí ìwé ìtàn àròsọ Àjà Ló Lẹ*rù* tí Òkédìji kọ jẹ́ ìtàn àkàtúnkà. Àwọn ohun ti àwọn onímọ̀ ṣì lè wò nínú iṣẹ́ ọpọlọ yìí pọ̀ dẹ́nu. A rí i pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òǹkọ̀wé kò ṣiṣẹ́ lórí mọfọ́lọ́jì èdè Yorùbá síbẹ̀ iṣẹ́ yìí fi hàn pé iṣẹ́ lítíréṣọ̀ àti gírámà wọnú ara wọn ni bí ẹran ti wọnú eegun tí eegun sì wọnú ẹran.

## Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí


Adékẹ́yè, B.F. (2015). *Issues in Yorùbá Categorization*. Germany. LAP Lambert Academic Publishers

Adékẹ́yè, B.F. (2016). *Gírámà Tuntun Ní Èdè Yorùbá*. Aba: National Institute for NigerianLanguages.

Arókoyọ̀, B. E. (2013). *Unlocking Morphology*. Ìlọrin: Unilọrin Press.

Awóbùlúyì, O. (2008). Ẹ̀kọ́ Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀ Yorùbá. Àkúrẹ́: Montem Paper

Awóyalé, Y. (1974). Studies in the Syntax and Semantics of Yorùbá Nominalization. Doctoral Dissertation, University of Illinois, Urbana Champaign

Bámgbóṣé, A. (ed). (1992) *Yorùbá Meta-Language (Èdè Ìperí Yorùbá)*.Ìbàdàn : University Press PLC

Egbokhare, F. (2004). Language and Politics in Nigeria. In Kọ́lá Owólabí & Dasylva, A. (eds) (2004) *Forms and Functions of English and Indigenous Languages in Nigeria: A Festchrift in Honour of Ayọ̀ Bánjọ*. Ìbàdàn: Group Publishers. Pp 507 – 522.

Ògúndèjì, P. A. (2004) Multilingual Situation in Nigerian Drama: A Perspective. In Kọ́lá Owólabí & Dasylva, A. (eds) (2004) *Forms and Functions of English and Indigenous Languages in Nigeria: A Festchrift in Honour of Ayọ̀ Bánjọ*. Ìbàdàn: Group Publishers. Pp. 670 -692

Òkédìjí, O. (2012) Àjà Ló Lẹrù . Lagos. Learn Africa PLC
Ọlábọ̀dé, A. (1985). Stylitics and Problems of Literary Interpretation in Yorùbá. In K. Williamson (ed) (1985) *West African Languages in Education*. Vienna: Afro-Pub. 229 -250.
Ọlátẹ́jú, A. (2012). Current Issues and Trends in African Verbal Stylitics: The Yorùbá Example. In J. S. K. Makokha, Ogone John Obiero and Russel West-Pavlov (eds) (2012). *Style in African Literature Essays on Literary Stylistics and Narrative Styles*. New York: Rodopi.pp. 59 – 70.
Owólabí, K. (1984). Ìsọ̀rí Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a Ṣẹ̀dá Nípa Lílo Àfòmọ́-Ìbẹ̀rẹ̀ àti atọ́ka Àfikún Nínú ÈdèYorùbá. *LÁÀŃGBÁSÀ: (Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá.)* 1 pp.61-101
Owólabí, K. (1985). Àpètúpè Gẹ́gẹ́ Bí Ète Fún Ìṣẹ̀dá Ọ̀rọ̀-Orúkọ Nínú Èdè Yorùbá.*LÁÀŃGBÁSÀ: (Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá.)* 2 pp.69-104
Owólabí, K. (1992). Ṣíṣe Àtúpalẹ̀ Lítíréṣọ̀ ní Ìbámu Pẹ̀lú Gírámà Onídàrọ Olófin Àyídà: Ewì Gẹ́gẹ́ Bí Àpẹẹrẹ . in A. Ìṣọ̀lá (ed) (1992) *Findings in Yorùbá Studies, J. F. Ọdúnjọ Memorial Lectures Series*. Pp 83 – 99.
Owolabi, Kola. 1995. More on Yorùbá prefixing morphology. In Owólabí, Kọ́lá ed. *Essays in Honour of Ayọ̀ Bámgbóṣé*: 92-112.
Táíwò, O. (2014). *Mọfọ́lọ́jì.Àtúnṣe Kejì*. Ìbàdàn: Universal Akada Books Ltd
Tinuoye, M. 2000. *A Contrastive Analysis of Yorùbá and English Morphology*. Ìbàdàn:Tafak Publications.